**February 2021**

**Agbára Gbọ́dọ̀ pàrọ̀ ọwọ́**

**(ỌRẸ ÀKỌ́SO)**

**ORIN:**

**ỌRỌ AGBÁRA**

1. Àwọn ajẹnirun sàtánì, tí wọ́n n ṣiṣẹ́ lórí igi àyànmọ́ mi,Ọlọ́run Èlíjà yóò pa yin run lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run mi, bàabá mi,nípa àánú yín, ẹ dìde nítorí àyànmọ́ mi, kí ẹ sì fi hàn pé ẹ̀yin ni Ọlọ́run mi nítòótọ́, ní orúkọ Jésù.
3. Agbára yówù, tí a yàn láti tọpinpin ìràwọ̀ mi fún ibi lọ́dún yìí, ọfà ikú òjijì,ló máá jẹ́ tìrẹ lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo aásìkí mi tí a ti gbé sin,gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, lónìí, o máa gba ìfọwọ́-tọ́ agbára àjíǹde Jésù kìrísítì olúwa, kí o sì padà tọ̀ mí wá, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo àgbà ìkà, tí a ti yàn láti gbé ògo àyànmọ́ mi sin, gba ìdájọ́ ikú, ní orúkọ Jésù.
6. Ìwọ àyànmọ́ mi,gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, dìde kí o sì tàn, ní orúkọ Jésù.
7. Agbára yówù, tí a yàn láti pín ògo àyànmọ́ mi pẹ̀lú àjèjì, kú báyìí, ní orúkọ Jésù.

**ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run dìde, kí o sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí òkè iná àti ìṣẹ́ ìyanu.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àlàáfíà àti ìtẹ̀síwájú,síji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Agbára òkùnkùn yówù, tí a yàn láti ya àyànmọ́ mi sí wẹ́wẹ́,kìnnìún júdà, ya wọ́n sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
5. Kìnnìún òkùnkùn, tí a yàn láti ṣe ayé mi básu-bàsu, gbiná, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn agbára, tí wọn ń gbèrò láti fi òròró ẹ̀gàn àti ìtìjú baputíìsì mi, kú pẹ̀lú òróró rẹ, ní orúkọ Jésù.
7. Ọfà àdúrà mi, dìde, mú kúrò gbogbo ọ̀tá ìpele mi tókàn, ní orúkọ Jésù.

**ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ**

**Jòhánù kìn-ín-ní 1:9** Bí àwa bá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa, olóòótọ́ àti olódodo ní òun,láti dárí ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá, àti láti wẹ̀ wá nù kúró nínú àìsòdodo gbogbo.

**Kọ́ríntì kì-iń-ní 15:57** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run ẹni tí ó fi ìṣẹ́gun fún wa nípa Olúwa wa Jésù Kírísítì.

**Orin Dáfídì 149:7** Láti san ẹ̀san lára àwọn kèfèrí,àti ìjìyà lára àwọn ènìyàn.

**Orin Dáfídì 149:8** Láti fi ẹ̀wọn de àwọn ọba wọn,àti láti fi ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ irin de àwọn ọlọ̀tọ̀ wọn.

**Orin Dáfídì 149:9** Láti ṣe ìdájọ́ wọn,tí a ti kọ̀wé rẹ̀, ọlá yìí ni gbogbo ènìyàn mímọ rẹ̀ ní. Ẹ fi ìyìn fún Olúwa.

**Jóẹ́lì 2:25** Èmi ó sì mú ọdún wọnnì padà fún yín wá, èyí tí èésú òun irú kòkòrò jewéjewé, àti irú kòkòrò kejì, àti irú kòkòrò jewéjewé mìíràn ti fi jẹ, àwọn ogun ńlá mi tí mo rán sí ààrín yín.

**Jóẹ́lì 2:26** Ẹ̀yin o "sì jẹun lí ọ̀pọ̀lọpọ̀, ẹ o sì yo, ẹ ó sì yin orúkọ OLÚWA Ọlọ́runyín, ẹni tí ó fi ìyánu bá yín lò, ojú kì yóò ti àwọn ènìyàn mi láé.

**Jóẹ́lì 2:27** Ẹ̀yin ò sì mọ̀ pé , èmi wà láàrin Israẹli, àti pé: èmi ni OLÚWA Ọlọ́run yín, kìí ṣe ẹlòmíràn: ojú kì yóò ti àwọn ènìyàn mi láé.

**Romu 8:37** Ṣùgbọ́n nínú gbogbo nǹkan wọ̀nyì àwa ju ẹni tí ó ṣẹ́gun lọ nípa ẹni tí ó fẹ́ wa.

**Deutáérónómì 20:4** Nítorí pé OLÚWA Ọlọ́run yín ń bá yín lọ, láti bá àwọn ọ̀tá yín jà fún yín, láti gbà yín là.

**Romu 8:31** Ǹjẹ́ kí lí àwa ó ha sì wí sí nǹkan wọ̀nyí? Bí Ọlọ́run bá wàfún wa, tan ni yóò kọjú ìjà sí wa?

**Romu 8:39** Tàbí òkè tàbí ọ̀gbun, tàbí ẹ̀dá mìíràn kan ni yóò le yà wá kúrò nínú ìfẹ́ Ọlọ́run, tí ó wà nínú kírísítì Jésù Olúwa wa.

**Isaiah 41:13** Nítorí èmi OLÚWA Ọlọ́run rẹ yóò di ọwọ́ ọ̀tún rẹ mú, èmi yóò wí fún ọ pé, má bẹ̀rú; èmi ó ràn ọ́ lọ́wọ́.

**Éfésù 6:10** Lákòótán , ará mi, ẹ jẹ́ alágbára nínú Olúwa, àti nínú agbára ipá rẹ̀.

**Orin Dáfídì 108:13** Nípaṣẹ̀ Ọlọ́run ni àwa ó ṣe akin; nítorí òun ni yóò tẹ àwọn ọ̀tá wa mọ́lẹ̀.

**Jòhánù kìn-ín-ní 5:4** Nítorí olúkúlùkù ẹni tí a bí nípa ti Ọlọ́run ó ṣẹ́gun ayé: èyí sì ni ìṣẹ́gun tí ó ṣẹ́gun ayé, àní ìgbàgbọ́ wa.

**Kọ́ríntì kejì 10:4** (Nítorí ohun ìjà wa kì í ṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó ní agbára nínú Ọlọ́run, láti wó ibi gíga palẹ̀)

**Kólósè 2:15** O sì ti já àwọn ìjábọ àti agbára kúro ní ara rẹ̀, ó sì ti dójú tì wọ́n ní gbangba, ó ń yọ àyọ̀ ìṣẹ́gun lóri wọn nínú rẹ̀.

**Luku 10:19** Kíyèsi èmi fún yín ní agbára láti tẹ ejò àti àkéekèé mọ́lẹ̀, àti lórí gbogbo agbára ọ̀tá: kò sì sí ohun kan bó ti wù kí ó ṣe, tí yóò pa yín lára.

Òwe 24:16 Nítorí pé olóòótọ́ á subú nígbà méje, á sì tún dìde: Ṣùgbọ́n ènìyàn búburú yóò subú sínú ibi.

**ÀWỌN ÀDÚRÀ KÍ Á TÓ SAN ỌRẸ ÀKỌ́SO**

**Na ọrẹ náà sókè, kí o sì gbàdúrà báyìí:**

"Bàbá, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ, pé ẹ fún mi ní àǹfààní yìí, ipá àti ọgbọ́n láti ní èso yìí. Mo mọ̀ yín mo sì jọ́sìn fún yín pẹ̀lú ọrẹ yìí gẹ́gẹ́ bí orísun kan soso tí owó ti ń wọlé fún mi. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ yin nítorí nígbà kan rí mo ti sọnù, ṣùgbọ́n báyìí a ti wá mi rí. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ yin fún ìgbàlà ọkàn mi.

Bí mo ti ṣe ń san ọrẹ àkọ́so yìí báyìí, ẹ tẹ́wọ́ gbàá, Olúwa, nípa agbára nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù. Nípa ọrẹ yìí, mo fẹ́ jẹ́ kí ẹ mọ̀ pé ẹ̀yin ni ẹni ìsiwájú mi. Ọlọ́run dìde, kí o sì lo ọrẹ yìí gẹ́gẹ́ bí kọ́kọ́rọ́ sí ìsọdi-púpọ, ìsọdi-gbígbòòrò, ìgbéga àti ojúrere- tí-kòwọ́pọ̀ mi. Nípa ọrẹ yìí, , jẹ́ kí agbára ìfisòfò di píparun kúrò nínú ayé mi, gbàmílà kúrò lọ́wọ́ ìpànù yówù, kí o sì fi ìbùkún tí owó kò le è rà bo ayé mi.

Nípa ọrẹ yìí, mo so ara mi mọ́ ihò-ìtẹ̀bọ̀ ètò ìsúná ọ̀run tó sí, àlàjá tí kò wọ́pọ̀, ìjẹgàba ìṣerere, ojúrere-tí-kò-wọ́pọ̀, àṣeyọrí tó gọtiọ àti ìṣẹ́gun pátápátá, ní orúkọ Jésù.

Bí mo ti ń fi ọrẹ àkọ́so yìí sílẹ̀, jẹ́ kí ìyàsí-mímọ́ rẹ̀ sàn wọ inú àwọn ọ̀nà yókù tí owó ń gbà dọ́wọ́ mi. Olúwa, taari mi lọ síbi ipò àtòkèwá rẹ, ibi gan an, ìfòróró-yàn àti ọgbọ́n fún ayé mi. Jẹ́ kí wàrà àti oyin ti ayé yìí gúnlẹ̀ sóókan àyà mi.

Èyí ni mo gbà ládùúrà, ní orúkọ Jésù kírísíti Olúwa álágbára wa, Àmín.